**Akiyesi**

Anfọ Eniti yio ma ba wa tu Iwe Irohin Imọlẹ. Ni agbegbe Ilọrin tabi Ilumiran. E lọ si ọdọ Ogbeni:- A. O. AJIBOYE Esq. Ni Ọja Gambari Ilọrin

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**AKIYESI**

Ki ẹnikẹni ti oba fẹ ra Iwe Irohin Imọlẹ ni Abeokuta ma lọ ra lọdọ Asoju wa Ogbeni Francis Ogundimu 6, Ake Street, Abeokuta.

VOL. III No. 131 MONDAY J NUARY 4 — JANUARY 10 1960 KỌBỌ KAN (1d)

# Ogbeni Benson Sana mo Gbogbo Iwe Irohin

Ogbeni Theophilons Owolabi Sobowale Benson fi iwe ipe ranse si gbogbo awon Oniwe Irohin wipe, ki nwon pade on ni ile Egbe Mainland Hotel on oro kan lati ba won so ati pe nkan mimu yio sole lehin ti nwon ba pari oro osis na tan.

Owe kan sọ wipe openi lo nṣe ọla, ko sí ẹniti o mo iru ọrọ ti Minister Benson fẹ sọ ati wipe ko peni bẹ ri. Nitorina gbogbo awọn oniwe irohin mura kiakia lati lọ da lohun ninu ọdun titun yi, boya nkan yio ṣe ẹnu rẹ.

Si iyalẹnu gbogbo awọn oniwe irohin, ina ni ọgbeni Benson bẹre si sa mọ wọn lati fi dẹruba wọn o wipe, ẹnyin Oniwe irohin, ki ẹ lọ ṣọ ara nyin lẹnu ọjọ mẹta yi, enikẹni ninu nyin ti o ba ṣọrọ ti ko nṣe otitọ on yio kọ ni ọgbọn.

O sọ wipe gẹgẹbi mo ti fi ọrọ yi ye ẹnyin oniwe irohin to nko ni ṣe suru rara bi iwe irohin kan ba tako Ijoba, emi yio rojo iwe irohin bẹ Ijọba si wipe ki nwọn ṣe ẹtọ fun. O tun sọ wipe ọrọ ti agbọ, on ko fẹ mọ, afi eyiti o soju oniwe Irohin lati ri ododo ọrọ na.

Ibere tiwa nihin ni wipe, awọn Iro.hin ti angbọ nipa awọn ohun ti o nṣẹlẹ nilu okere, ey'ti a ntẹ sinn iwe irohin fun kika, a rope gbogbo iru irohin bawọnni yio ma ṣe iṣoju Ọgbẹni Benson.

Nigbati o pari ọrọ rẹ tan ni awọn oniwe Irohin da oporo ibere boo, ni ọkan ko jọ kan, tobẹ ti ẹnu rẹ fi kọ jẹjẹ ti ko le dahun, iba ohun ti o nwi ni wipe "Abọ ọrọ to fun ọmọluwabi" nigbati nwọn bere wipe kini ohun ti o fẹ sọ nipa ọrọ rẹ ti o sọ pe, ki enia ma tako Ijọba buruku-buruku.

Diẹ ninu awọn iwe Irohin ti o wa nibẹ niwọn yi:- Daily Times, Sunday-Times, Irohin Imọlẹ Daily-Service, New York Times West African Pilot, Daily-Telegraph, Sunday Express The Truth, Akede Eko, Irohin Yoruba West African News Service, ati United-Press International.

Bi Benson ti nsọrọ bakanna ni awọn Oniwe irohin n gbo ni oohun, Benson nsọ asọisimi, awọn oniwe irohin ko fi ara mọ Nikẹhin Alhaji Jọsẹ sọ sọ wipe a gbọ ohun ti o wi, ṣugbon a ko gba ni won ba dide.

## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alata todaraju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tẹlẹrilọ lẹyin ata lilọ o tun le lọ Igbado ati Ọka Baba ati Ẹwa - ere orisirisi.

**£45 Ni a nla** Pẹlu Enjinni Pẹtrol tabi ati pẹlu Ẹletiriki Mutọ.

O WA NI SOBU:-

**Akoshile Brothers,**
5, Balogun Street West,
P. O. Box 599.
Phone No., 24395. LAGOS.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pa taki ta ṣe ni Aṣepe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pelu idaniloju fun Awọn iṣẹ ribiribi ti o ti nṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona ikọ, otutu, Aiperi, Osi inu ọmọde, jẹdi i ẹ d i Kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsan fọnfọn, o nmu ki ehin hibu jẹ irọ run fun awọn ọmọde, osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko se mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ, tete lọ ra ti ọ ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d
LILO RE:- Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*
A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West Lagos Nigeria. Phone 22515

34, Docemo Street Lagos Phone 24247

**IMOLE**

EGIN OKO WA
IMOLE DE OKUNKUN PARADA
*Editorial Works & Office*
**16, Bamgbose Street, Lagos.**
**Telephone:- 21985**
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street,

## Odun miran fun de

TAN IMOLE SI OKUNKUN WA OLUWA, KI O SI JE KI ODUN ODUNNI JE RERE FUN GBOGBO WA.

Awa oniwe Irohin Imole yio tun beresi ki gbogbo enyin okawe wa jakejado pe e ku afojuba odun titun ti o wole yi, ki Oluwa ko se odun na labo fun gbogbo wa, a ko ni gbe oku wo ile wa, bena ni Oluwa ko ni jeki won gbe oku jade ninu ile olukuluku wa, ki Oluwa ninu anu Re se odun na ni odun ayo fun gbogbo wa.

Ki a to tesiwaju ninu oro wa, a ki awon Oselu wa pe nwon ku ise, nwon si ku ogbon ori, ki Oluwa si tun fun won ni imo kun Imo won. Oluwa ko ni kodi aimo si won

Awa oniwe Irohin Imole nilati fi ye nyin wipe asiko to fun gbogbo wa lati di amure wa giri lati se ise ninu ilu wa, olukuluku wa ni o ni ise ti a nilati se, ati iwo ti o gbo ede oyinbo, ati iwo ti ko gbo ede oyinbo, aye wa fun nyin ninu awon iwe Irohin ni ede yoruba ti ki yio na yin ni owo, paapa awa oniwe Irohin Imole ti beresi se eto lati asiko yi lo lati so oju ewe iwe wa di mefa tabi mejo bi a ba ti ori irohin iwuri si lati odo enyin okawe wa wa.

A fe ki e ranti oro pataki ti Olotu Apapo ile Naijiria Alhaji Abubakar Tafawa Balewa so ni iwoyi odun ti koja nigbati o nki gbogbo ilu ku ewu odun titun, o so ninu oro re ba yi pe, Aye wa fun olukuluku lati gbe ogo ilu re ga nipa kiko edun okan re si inu iwe Irohin ti o njade lojojumo tabi eyiti o njade ni osose ni ede yoruba.

Pupo ninu wa ni ko mo ohun ti awon iwe irohin nwonyi je, yio je ohun ayo fun wa, na pa awa omo KARO-O-JIRE, opolopo wa lo nfi awon iwe Irohin wonyi da agunla, eyi ko si dara rara.

## Oro na ko ni je be mo

KADUNA.

Gegebi ileri ti Serdauna Alhaji Ahmadu Bello se wipe nigbati o ba di inu odun 1961 gegebi on ti ni ero ni okan ara on, on fe lati yowo yose kuro ninu ise iselu, ki on si mojuto idile on ti ise oba Sokoto.

Sugbon lati igbati on ti kede oro yi ni on ti nri orisirisi iwe gba, waya, ati orisirisi ise lori oro isoro ti won ngba on ni imoran wipe ki on ma se be, pelupelu awon igbimo apejo (Assembly) ni igboro ilu Kaduna tun gba on ni imoran wipe ki on maiti ni ero yi lokan rara.

Lati igbati mo ti ri opo enia ti nwon gba mi ni imoran, okan mi yi pada, nko si ni fi ise Oselu sile ni odun 1961 gegebi mo ti wi tele.

Emi yio ma ba ise iselu mi niso titi ti akoko yio fi to ti awon omo egbe mi yio fi wi fun mi wipe ki nyo owo kuro ninu iselu, Sardauna Sokoto so fun awon omo egbe re pe piparapo ti on papo mo egbe N.C.N.C., on se eyi lati fi han wipe Hausa ko lodi si isokan ile Naijiria.

## Ere ekute ati Ologbo ni won nse

ZARIA.

Obinrin kan ti o je Iyalode fun awon egbe NEPU

WO OJU EWE KETA



O BẸRẸ LATI OJU EWE KEJI

ti orukọ rẹ njẹ Malama Gambo sọ wipe, on ko ri iru ọrẹ ti awọn ẹgbẹ N.C N.C. ati N.P.C mba ẹgbẹ N.E P.U ṣe yi ri, loju on o jọ ere Ologbo ati Ekute.

O yẹ ki Aminu Kano olori ẹgbẹ N. E. P. U ati Azikiwe olori ẹgbẹ NCNC ṣe iranti ogunlogọ awọn ọmọ ẹgbẹ N.E.P.U. ti o mbẹ ninu igbekun awọn Hausa N.P.C. lati bi ọdun mẹjọ sẹhin wa.

Irohin kan wa pe awọn ti o ṣe atilẹhin fun Adisa wọle nilu Ibadan ni a tilẹ ṣe jade kuro ninu ẹgbẹ N.C.N.C., ẹnikan bere ni ọwọ Anyiam wipe kini o ti ro ti awọn to ṣe atilẹhin fun ẹgbẹ N P.C si?

O dahun wipe, ati ẹgbẹ N.E.P.U., ati ẹgbẹ NCNC, ati ẹgbẹ N.P.C., nwọn si nba ara wọn ṣere ni, ere Ekute ati Ologbo ni nwọn si mba ara wọn ṣe lọwọ, bi o ba si ya NPC yio ja wọn silẹ.

**E ma polowo oja yin sinu Irohin Imole**

# Bere fun Egbogi Jamani ti won npe ni:- " ERMELINDA " (Fun Itoju tabi Ajo Obirin) Ni pataki

Egbagbeje orişirişi egbogi lo kakiri igboro ilu Eko tabi ni Naijiria ti wọn nta ti wọn si npe ni egbogi fun AJO OBINRIN, şugbọn wọn ko le şişẹ daradara rara, eyi yi lo mu wa kọ iwe pataki si awọn ogbologbo ati ọjọgbọn olori Onişegun ni ilu Jamani wipe a nfe ojulowo egbogi haunhaun atamatase fun "OBINRIN" ti yio jẹ "GBOGBONŞE" fun orisirişi Amodi tabi Aisan to ba nyọ Obinrin lẹnu ni "INU". Eyi lo mu awọn olori dọkita elegbogi Jamani wa idi egbogi "ERMELINDA" yi kọn, ti wọn si şe wa fun ajo tabi itoju orişirişi aisan tabi amodi ti o ba nmu idiwọ tabi ti o nyọ obinrin lẹnu NINU gbogbo. Orişi egbogi mẹta lo wa ninu pali rẹ, atamatase si ni iru rẹ kosi ni gbogbo şọbu ti o wa ni Eko tabi ni Naijiria rara o. Owo pali rẹ kan jẹ ponun mejiabọ, owo ọkọ jẹ şilemẹta-abọ pelu.

Şe iranti wipe ohun ti o ba dara yio wọn, şugbọn owo rẹ yio funa iyẹn daju ti o ba d a n w o. Egbogi yi ti ran pupọ obinrin lọwọ, yio ran ọ lọwọ pẹlu, inu rẹ a si dun jọjọ nigbati iwọ na ba ri alafia ati ere rẹ lagbara Olọrun o, ma fi owo re şe ofu mọ rara o.

Bere Egbogi "ERMELINDA" ni şọbu awọn ti a da orukọ ni isalẹ iwe yi ki o si şọra gidigidi ki awọn eleru ma lọ ta Adamọdi omiran fun ọ, maşe gba rara.

Owo pali kọn Ponun meji abọ

Owo Okọ (Postage) Şile mẹta abọ

Bere ojulowo Egbogi omiran fun orişirişi amodi ti o ba fẹ ni şọbu awọn:—

Waterloo Medicine Stores
8, PalmChurch Street P. O Box 333
Lagos Nigeria Phone 22878

Ati Pelu Ni Sobu Arabinrin:-

MRS. C. O. BABAJIDE,
NEAR HEALTH OFFICE. IBADAN

ati ni ABIMBỌLA MEDICINE STORES
B29 Okesha Street Ilesha

AKIYESI:— Ri daju gbangba wipe şọbu ti wọn nta jo gbe ranşẹ lọra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU jọta adamọdi tabi orişi omiran fun ọ o, maşe gba rara.


**NJẸ O NI OTUTU IBA**










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro gbe koro "ASPRO" meji mi
ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA

